# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kéjìlá, Ọdún 2023**

## Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́

**Ìsìn Ìfòròróyàn Ọdọọdún**

Oṣù Kéjìlá, Ọdún 2023 **– AGBÁRA LÁTI ṢE ÌDÁJỌ́ (2)**

ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀

1. **Ọlọ́run ‘bùkún a yìn Ọ́**

A nkéde or’ọ̀fẹ́ Rẹ
‘Wọ olúgbalà Wọ mímọ́
Ògo f’órúkọ nlá Rẹ

Ògo, ni fún ọ́kọ Rẹ,
Ológo ni orúkọ Rẹ
Ògo, ni fún Ọ́kọ Rẹ
Ológo ni ókọ Rẹ,

2. Olùràpadà Olúwa

Ìmọ́lẹ̀ àti àìlópin
Káwọ́n mímọ́ gbogbo kọrin
Òdodo àt’iyìn Rẹ

3. Láti ìtẹ́ ògo t’ọ̀run

Dé orí àgbélèbú
Ìwọ kú ikú ‘ràpadà
Láti gba ẹlẹ́ṣẹ̀ là.

4. Wá Ìwọ Olúwa Ìyè

Wá gúnwà ní ìtẹ́ Rẹ

Wá láti jọba títí láí
Kí ijọ̀ba jẹ́ Tìrẹ.

1. **Jí, sọ agbára Rẹ d'ọ̀tun**
Gbé hàmọ́ra ogun rẹ wọ̀;
A o ṣẹ́gun gbogbo ọ̀tá
Krístì yó sì jọba.

Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba

2. Ó ti pẹ́ t'áwọn ọmọ Rẹ
Tí nṣẹ 'yapa lórí ẹ̀kọ́;
Wọ́n gbàgbé pé l'órí ṣọ̀kan
Ni Òn lo ayé Rẹ

3. Ẹ papọ̀ ní agbára Rẹ
Ayè yin yó sì jẹ èrè
Láìpẹ́ ẹ ò ní ìṣẹ́gun
'Torí Kríst'y'o jọba

4. Ó yẹ ka ṣiṣẹ́ f’Ólúwa,
Iṣẹ́ wa kò jẹ́ asán;
A kò gbọdọ̀ padà s’ẹ́yìn,
‘Torí Krístì y’ó jọba

## **<u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>**

1. Agbára ìyówù, tí wọ́n yàn láti kórajọ lòdì sí ògo mi, yóò gbiná lónì, ní orúkọ Jésù.
2. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo agbára tí ó wà nídì àwọn iṣòro mi olóríkunkun yóò gba itijù lónì, ní orúkọ Jésù.
3. Ìpìlẹ̀ ìkùnà tí wọ́n pèsè fún ìdílé mi yóò gbiná lónì, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára tó n fí ìgbà gbogbo gbógun lòdì sí ayànmọ́ mi, yóò ṣubú lulẹ̀, yóò sì kú lónì, ní orúkọ Jésù.
5. Adigunjalè ayànmọ́, tí wọ́n yàn lòdì sí ọkọ̀ ayànmọ́ mi, akókò rẹ dópin lónì, túmisílẹ̀, ki o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Ara mi, ọkàn mi, ẹ̀mi mi, ti gbogbo májèlé sátánì jáde, ní orúkọ Jésù.
7. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, àwọn ángẹ́lì Ọlọ́run Alààyè yóò fi iṣẹ́-ìyanu tí n kò retí ṣàwárí mi lónì, ní orúkọ Jésù.

## **<u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>**

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.

3. Gbogbo ọba Ùssíàh, tí wọ́n yàn láti ṣi ògo ayànmọ́ mi nípò, kú, ní orúkọ Jésù.
4. Òróró tí yóò jẹ́ kí wọ́n kede mi, ki wọn tun ṣàjọyọ̀ mi, bàlé aye mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo orìṣà ìdílé, ti ó kọ jalẹ latì jẹ ki ògo ayànmọ́ mi lọ, àkokò rẹ ti dópin, kú nipa ina, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo irúgbìn ikunà ati itiju, ti o walẹ jin sínú ìpìlẹ̀ mi, gbiná báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí àwọn ọ̀tá Rẹ nínú ayé mi túká, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**2 Kọ́ríntì 2:14** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹnití nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wa nígbàgbogbo nínú Krístì, tí Ò sí nfi orun ìmọ̀ Rẹ hàn nípa wa níbigbogbo.

**1 Kọ́ríntì 15:55** Ikú, oró rẹ dà? Iṣà òkú, ìṣẹ́gun rẹ dà?

**Jóṣúà 10:8** OLÚWA sì wí fún Jóṣúà pé, Má ṣe bẹ̀rù wọn: nítorítí mo ti fi wọ́n lé ọ lọ́wọ́; kì yóò sí ọkùnrin kan nínú wọn tí yóò lè dúró níwájú rẹ.

**Ìfihàn 12:11** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùntàn ná, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

**Hébérù 4:12** Nítorí  ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yè, ó sì lí agbára, ó sì mú ju idàk'dà olójú méjì lọ, ó sì n gúnnni àní títí dé pípín ọkàn àti omi níyà, àti òríkè àti ọ̀rá inú egungun, òn sì ni olùmọ̀ èrò inú àti ète ọkàn.

**Fílíppì 4:13** Èmí lè ṣe ohun gbogbo nínú Krístì ẹnití nfi agbára fún mi.

**Rómù 8:1** Ǹjẹ́ ẹ̀bi kò sí nísisìyí fún àwọn tí ó wà nínú Krístì Jésù, àwọn tí kò rìn nípa ti ara, bíkòṣe nípa ti Ẹ̀mí.

**Rómù 8:28** Àwa sì mọ̀ pé ohun gbogbo li ó n ṣiṣẹ́ pọ̀ sí rere fún àwọn tí ó fẹ́ Ọlọ́run, àní fún àwọn ẹnití a pè gẹ́gẹ́ bí ìpinnu rẹ̀.